# ÌTÀN ÌJÌNLẸ̀ NÍPA ÌSỌTẸ́LẸ̀

## ỌBA NÁÀ NBỌ̀

## Ìtàn ...

**2 Awọn Ọba 11:1-21**

Ataliah tí ó jẹ ọba obinrin ní ilẹ̀ Juda jẹ́ ẹni búburú, ó sì tún burú ju ìyá rẹ̀ Jesebeli lọ. Nígbàtí ọmọ rẹ̀ Ahasiah kú, lẹsẹ̀-kẹsẹ̀ ló gba ìjọba pẹlu ipá ti ó si pa gbogbo awọn ọmọ-ọba ti wọn le è jọba ni ipò rẹ̀. "Ṣùgbọ́n Johoṣeba, ... arabinrin Ahasiah mú Joaṣi ọmọ Ahasiah, o si ... nwọn sì pa á mọ́ ... kúrò lọ́dọ̀ Ataliah, ti a kò sì fi pa á. A sì pa á mọ́ pẹlu rẹ̀ ni ile OLUWA li ọdún mẹfa. Ataliah sì jọba lorí ilẹ̀ náà." 2 Awọn Ọba 11:2,3.

Fún ìwọ̀n ọdún mẹfa, awọn olótitọ eniyan mọ̀ wípé a pa ọmọ-ọba mọ́ ninu tẹmpili Ọlọrun. Jehoiada, olórí alufa fẹràn ọmọ náà, ó si tọ́ Joaṣi gẹ́gẹ́ bi ọmọkunrin rẹ̀. Fún ọdun mẹfa Jehoiada pinnu, o sì gbàdúrà fún àkókò ti yio fi ọmọ náà hàn fun awọn eniyan gẹ́gẹ́ bi ajogún tòótọ́. Lakotan, alufa arúgbó yi, sì pe awọn ti o ṣe fọkàn-tán ninu awọn olórí-ogun jọ ni ìkọ̀kọ̀, ó si fi ọmọkunrin kekeré ọmọ Ahasiah náà hàn wọn pé, ó wà láàyè. Wọn pinnu lati dúró di alẹ́ Ọjọ́bọ̀ (Friday) ní àkókò ti awọn olótítọ́ yio wà sí tẹmpili fun ìjọsìn Ọjọ́-Isinmi, lati fi ọdọmọde ọba náà hàn wọn. Pẹ̀lú ọmọ-ogun ọgọrun lẹ́gbẹ̀-ẹ̀gbẹ́, Jehoiada mu àrólé itẹ́ Dafidi wá síwájú wọn, ó sì fi hàn wọn. Ní ìbẹ̀rẹ̀, ẹnu yà wọn, ṣùgbọ́n nígbàtí wọn ri adé lori rẹ̀, nwọn pàtẹ́wọ́ wọn, nwọn sì wípé, Ki ọba ki o pẹ́." 2 Awọn Ọba 11:12.



Nibayi, bi Ataliah ẹni ibi ṣe gbọ́ ohùn fèrè ati bi awọn eniyan náà ti nyọ̀, ó sáré wá sí inú tẹmpili, bi o ṣe de ibẹ̀ ló rí wípé ìjọba búburú oun ti dopin. Ní ọjọ́ náà ni a pa oun ati awọn ọmọ-ẹhin rẹ̀, a sì gbé ìjọba fun Joaṣi.

Bibeli sọ fun wa pé, ọmọ Dafidi miran kò ní pẹ́ wá lati inú tẹmpili ọrun pẹlu ohùn ìpè lati gba ìjọba Rẹ̀ lotitọ́ ati pé ki Ó sì pa awọn ẹni búburú run.

Dí awọn alafo wọnyi lẹhin tí o ba ti ka ayọka Bibeli rẹ?

# Ẹ̀kọ́

Dí àwọn àlàfo wọ̀nyí, lẹ́hìn tí o bá ti kà ẹsẹ Bibeli kọ̀ọkan tán.

1. Tani ọba yi ti kò ni pẹ́ sọkalẹ̀ wá lati ọrun?
**Ifihan 14:14**
Mo sì wò, si kiyesi i, awọsanma funfun kan, ati lori awọsanma naa ẹnikan joko ti o dabi _______ - _______, ti oun ti adé wúrà li orí rẹ̀, ati dòjé mímú li ọwọ́ rẹ̀.

2. Ṣé Jesu yio wá ni idákẹ́jẹ́ nigbàtí Ó ba npada bọ̀ bí?
**1 Tessalonika 4:16**
Nitori Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ̀ lati ọ̀run wá ti oun ti _______, pẹlu ohùn olorí awọn angẹli, ati pẹlu _______ Ọlọrun; awọn òkú ninu Kristi ni yio si kọ́ jinde.
**Jeremiah 25:30**
Njẹ́ iwọ sọ asọtẹlẹ gbogbo ọ̀rọ̀ wọnyi fun wọn, ki o si wí fun wọn pé, OLUWA yio _______ lati òkè wá, yio si fọ ohùn rẹ̀ lati ibùgbé rẹ̀ mímọ́, ni kíkọ yio kọ sorí ibùgbé rẹ̀, yio _____ __ sori gbogbo olugbé ayé, bi awọn ti ntẹ ifunti.
**Orin Dafidi 50:3**
Ọlọrun wa mbọ̀, ki yio si _______; iná yio ma jó niwajú rẹ̀, ẹfufu líle yio sì ma jà yi i ka kiri.

Àkíyèsí: "Ẹfufu líle" túmọ̀ sí "ìdàrú tàbí ìjì. Ipadabọ̀ Jesu lẹẹkeji yio jẹ pẹlu ariwo ti kò ṣe júwe. Kò sí bojú-bojú ninu rẹ̀.

3. Kini ohun miran ti a le è fojúrí bi i ẹ̀rí fún ipadabọ Jesu?
**Ifihan 16:18**
Mànamána si kọ, a si gbọ́ ohùn, àrá sì sán, _______ nlá sì sẹ, irú èyítí kò sẹ rí lati ìgbàtí eniyan ti wà lori ilẹ̀, irú ìsẹ̀lẹ̀ nlá bẹ́ẹ̀ ti o si lagbara tó bẹ́ẹ̀.

4. Tani yio rí Jesu nígbàtí Ó bá npadàbọ̀?
**Matteu 24:30**
Nigbà náà li àmì Ọmọ-eniyan yio si fi ara hàn li ọrun; nígbà naa ni _______ _______ ayé yio kaanu, nwọn o si _______ Ọmọ-eniyan tí yio ma ti ojú ọrun bọ̀ ti oun ti agbára ati ogo nlá.
**Ifihan 1:7**
Kiyesi i, o mbọ̀ ninu awọsanma; gbogbo _______ ni yio si ri I, ati awọn ti o gún un li ọ̀kọ̀ pẹ̀lú; ati gbogbo orilẹ-èdè ayé ni yio sí maa pohùnrẹ́rẹ́ ẹkún níwájú rẹ̀. Bẹ́ẹ̀ naa ni. Amin.

Àkíyèsí: Èyí yeni yéké-yéké, bẹ́ẹ̀ni kò ní ìdàrú nínú. Gbogbo eniyan tó wà láyé yálà ẹni-ibi tàbí ẹni-rere, ni yio rí Jesu nígbàtí o ba npadà bọ̀. Ipejọpọ̀ ìkọ̀kọ̀ tàbí Rapture awọn eniyan Ọlọrun ni a kò sàlàyé ninu Bibeli.

5. Awọn wo ni yio wà pẹlu Jesu nígbàtí Ó bá nbọ̀ ni awọsanma?
**Matteu 25:31**
Nígbàtí Ọmọ-eniyan yio wá ninu ògo rẹ̀, ati gbogbo awọn ______ ______ pẹlu rẹ̀, nígbà naa ni yio joko lori itẹ́ ògo rẹ̀.

Àkíyèsí: Ìmọ́lẹ̀ ìpadàbọ̀ Oluwa ti a bá fi wé iná ìjọba, ṣe ni iná ìjọba dabi òjìjí òye iná láṣán. Ni iboji Jesu, ìmọ́lẹ̀ angẹli kan mú ki awọn olùṣọ́ Romu subú lulẹ̀ bi i òkú (Matteu 28:2-4). Ìmọ́lẹ̀ gbogbo awọn angẹli ọrun yio mu ipadabọ̀ Jesu lẹẹkejì mọ́lẹ̀ gidigidi ti kì yio si ẹni ti yio farasin. Àfikún si èyí ni yio mu ki ògo Jesu ati ti Baba wuni lọ́pọ̀lọpọ̀ (Luku 9:26). Ipadabọ̀ Jesu lẹẹkeji yio dàbí manamana ti ikọ lati ìlà-oòrùn, ti isi mọ́lẹ̀ de ìwọ̀-oòrùn (Matteu 24:27).

6. Kini ìmọ́lẹ̀ wíwá Jesu yio ṣe sí awọn ẹni búburú tó wà láyé?
**2 Tessalonika 1:7,8**
Ati fun ẹnyin, ti a npọ́n lójú, isinmi pẹlu wà, nígbà ifarahàn Jesu Oluwa lati ọrun wá ninu _______ _______ pẹlu awọn angẹli alagbara rẹ̀, Ẹniti yio san ẹsan fun awọn ti kò mọ Ọlọrun, ti nwọn kò si gbà ihinrere Jesu Oluwa wa gbọ́.
**2 Tessalonika 2:8**
Nigbana li a ó si fi Ẹni ẹ̀ṣẹ̀ nì hàn, ẹniti Oluwa yio fi eemi ẹnu rẹ̀ pa, ti yio si fi ifihan wíwá rẹ̀ sọ di _______.

7. Kini yio sẹlẹ̀ sí awọn olódodo ti wọn ti kú ni ipadabọ̀ Jesu?
**1 Tessalonika 4:16**
Nitori Oluwa tikararẹ̀ yio sọkalẹ̀ lati ọ̀run wá ti oun ti ariwo, pẹlu ohùn olorí awọn angẹli, ati pẹlu ipè Ọlọrun; awọn òkú ninu Kristi ni yio si kọ́ _______.

8. Ní ikorita yi, kini yio sẹlẹ̀ sí awọn alàáyè ati awọn ẹni mímọ́ tí ó ti jinde?
**1 Korinti 15:52,53**
Lọ́gán, ni iṣẹ́ju, nigba ìpè ikẹhin: nitori ìpè yio dún, a o si ji awọn òkú dide li aidibajẹ́, a o si pa wa lara _______, Nitori pe ara idibajẹ yi kò le ṣàìgbé àìdibajẹ wọ̀, ati ara kíkú yi kò le ṣaigbé ara àìkú wọ̀.

Àkíyèsí: Kò sí ẹnikan bikòṣe Ọlọrun ló ní àìkú bayi (1 Timoteu 6:15,16). Ṣùgbọ́n a o fi fún awọn olododo li ẹ̀bùn ọ̀fẹ́ ni ipadabọ̀ Rẹ̀ lẹ́ẹ̀kejì. A o pa wọn lara dà si ti ọrun, ara àìdibajẹ, ti yio dabi ti Jesu (Fillipi 3:20,21).

9. Lẹ́hìn ìpalárадà, kini yio sẹlẹ̀ sí awọn olododo?
**1 Tessalonika 4:17**
Nígbà náà li a ó sì _______ àwa ti ó wà láàyè ti o si kù lẹ́hìn _______ pẹlu wọn sinu awọsanma, lati pade Oluwa li ojú ọrun: bẹ́ẹ̀li awa o si ma wà titi lai lọdọ Oluwa.

Àkíyèsí: Awọn ẹni mímọ́ Ọlọrun yio pàdé Oluwa ni awọsanma. Jesu kò fi ẹsẹ̀ kan ayé nígbà wíwá Rẹ̀ lẹ́ẹ̀kejì, nitori náà, a kò ni ri I lori ilẹ̀-ayé gẹ́gẹ́ bi ìgbàgbọ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀. Wíwá Rẹ̀ lẹ́ẹ̀kejì yio jẹ ni awọsanma ki ise lori ilẹ̀ ni a o ti ri I.

10. Ìkìlọ̀ jẹ́jẹ́ wo ni Jesu ṣe fun wa nípa ipadabọ̀ Rẹ̀ lẹ́ẹ̀kejì?
**Matteu 24:5**
Nítorí ọ̀pọ̀lọpọ̀ yio wá li orukọ mi, wípe, Emi ni Kristi; nwọn o si _______ _______ jẹ.
**Matteu 24:24,26**
Nítorí awọn _______ _______, ati èké woli yio dide, nwọn o si fi àmì ati ohun _______ nlá hàn; tobẹ́ẹ̀ bi o le ṣe e ṣe nwọn o tan awọn àyànfẹ́ pàápàá, Nítorí naa bi nwọn ba wí fun nyin pe, Wò ó, ó wà li aginjù; ẹ má lọ síbẹ̀: wò ó, o wà ni ìyẹ̀wù; ẹ máṣe _______.



YOR-SP3.indd 1 5/23/13 1:46 PM

Àkíyèsí: Satani yio fi ara rẹ̀ ṣe bi i wíwá Kristi nígbà kejì, yio sì farahàn bi i ẹni ògo lori ilẹ̀-ayé, yio si tan biliọnu eniyan jẹ. Jesu ti sọ fun wá pé Oun kò ni fẹsẹ̀ kan ayé ni ìgbà wíwá Rẹ̀ lẹ́ẹ̀kejì, ṣùgbọ́n yio dúró ni awọsanma. Awọn eniyan yio gbàgbọ́ ninu ìṣújú ẹtàn Satani, débi wípé ọ̀pọ̀ eniyan ni a ó tàn jẹ.

**11.** Kini yio yọ awọn olododo ti a kò fi ní tàn wọn jẹ?
**Isaiah 8:20**
Sí òfin ati sí ẹ̀rí: bi nwọn kò bá sọ gẹ́gẹ́ bi ________ yi, nítorí kò si ìmọ́lẹ̀ ninu wọn ni.

Àkíyèsí: A ò ní tan awọn eniyan Ọlọrun jẹ, nítorí pé wọn yio ti mọ bí Jesu yio ṣe wá nípa kíká Ọ̀rọ̀ Ọlọrun (Iṣe Awọn Aposteli 17:11). Iró ni gbogbo ifarahàn tí kò ba ti bá Ìwé-Mímọ́ mu, a sì gbọdọ̀ kọ ọ́. Jesu ti kìlọ̀ fun wa tẹ́lẹ̀.
**Matteu 24:25** Wò ó, mo wí fun nyin tẹ́lẹ̀.

**12.** Ṣé kò sí ewu ninu lílọ lati wo èké Kristi?
**Matteu 24:26**
Nítorí naa bi nwọn bá wí fun nyin pe, Wò ó, ó wà li aginjù; ẹ ______ lọ ______: wò ó, o wà ni ìyẹ̀wù; ẹ máṣe gbàgbọ́.

**13.** Kini a le è mọ̀ nípa àkókò ipadabọ̀ Jesu?
**Matteu 24:36**
Ṣùgbọ́n níti ọjọ́ ati wákàtí naa, kò sí _________ ti o _____ ọn, awọn angẹli ọrun kò tilẹ̀ mọ́ ọn, bikoṣe Baba mi nikanṣoṣo.
**Matteu 24:33**
Gẹ́gẹ́ bẹ́ẹ̀ li ẹnyin, nígbàtí ẹnyin ba rí gbogbo nkan wọnyí, ki ẹ mọ̀ pe o _______ etílé tán lẹhìn ìlẹ̀kùn.

Àkíyèsí: Ọlọrun nìkan ló mọ̀ àkókò wíwá lẹ́ẹ̀kejì. Gbogbo àkókò tí a yàn ni kò sowọ́pọ̀ pẹ̀lú Bibeli. Ṣùgbọ́n Jesu ti fi ye wa gbangba pé, bi a bá rí àmì wíwá Rẹ̀ ti o nwá si ìmúṣẹ (Matteu 24:4-51; Luku 21:8-33, ati 2 Timoteu 3:1-8), nígbà náà ni a ó mọ̀ pé dídé Rẹ̀ ti súnmọ́ etílé - li ẹ̀hìn ìlẹ̀kùn.

**14.** Kini awọn angẹli yio ṣe ni ipadabọ̀ Jesu lẹ́ẹ̀kejì?
**Matteu 24:31**
Yio sì rán awọn angẹli rẹ̀ ti awọn ti ohùn ipè nlá, nwọn o si _____ gbogbo awọn àyànfẹ́ rẹ̀ lati orí igun mẹrẹrin ayé jọ, lati ikangun ọrun kan lọ de ikangun kejì.

Àkíyèsí: Angẹli olutọ́jú rẹ (Matteu 18:10) ni yio kọ́kọ́ kí ọ ni ipadabọ̀ Jesu. Irú èrò ìbùkún wo ni èyí! Abájọ ti Bibeli fi pe bíbọ̀ Jesu lẹ́ẹ̀keji ni "ìrètí tí ó ní ìbùkún (Titu 2:13)!

**15.** Níwọ̀n bi o ti jẹ́ wípé, a wà láàyè ki Jesu tó padà dé lẹ́ẹ̀keji, báwo ni ìṣẹ̀lẹ̀ ologo yi yio ṣe kàn wá?
**Matteu 24:44**
Nitori naa ki ẹnyin ki o _______ silẹ̀: nitori ni wàkàtí ti ẹnyin kò rò tẹ́lẹ̀ li Ọmọ-eniyan yio dé.

**16.** Báwo ni a o ṣe san èrè fún àwọn eniyan ni bíbọ̀ Jesu lẹ́ẹ̀kejì?
**Ifihan 22:12**
Kíyèsí emi mbọ̀ kánkán; èrè mi si mbẹ pẹlu mi lati san fun olukuluku _______ bi iṣẹ́ rẹ̀ yio ti rí.



Àkíyèsí: A o gba awọn eniyan là nípaṣẹ̀ oore-ọ̀fẹ́ ṣùgbọ́n a o san èrè fun nípa ìwà wọn, ki iṣe nipa iṣẹ́ (Matteu 7:21-23).

**17.** Kíni awọn eniyan búburú yio wí nígbàtí Jesu bá dé?
**Ifihan 6:15-17**
Awọn ọba ayé ati awọn ọlọ́lá ati awọn olórí ogun, ati awọn ọlọ́rọ̀ ati awọn alagbara, ati olukuluku ẹrú, ati olukuluku ominira, si fi ara wọn pamọ́ ninu ihò-ilẹ̀, ati ninu àpáta orí òkè; Nwọn si nwí fun awọn òkè ati awọn àpáta naa pé, Ẹ wólù wa, ki ẹ si fi wa pamọ́ kúrò lójú ẹniti o joko lórí ìtẹ́, ati kúrò ninu ibinú Ọ̀dọ́-Agutan naa: Nitori ọjọ́ nlá ibinú wọn de; _______ si le _______?

Àkíyèsí: Ní ìgbà ilẹ̀ ríri búburú yi, awọn eniyan búburú - yio di arọ nitori ìbẹ̀rù - wọn yio yàn ki apata wó lu awọn ju ki wọn ko Jesu Ọba lójú láìròtẹ́lẹ̀.

**18.** Kíni awọn olododo yio wí nígbàtí Jesu bá farahàn?
**Isaiah 25:9**
A o si sọ li ọjọ́ naa pé, Wò ó, Ọlọrun wa li èyí; awa ti duro dè é, oun o si ____ wa _____: OLUWA li èyí: awa ti dúró dè é, awa o ma yọ̀, inu wa o si ma dù ninu ìgbàlà rẹ̀.

**19.** Kíni ìdí pàtàkì ti Jesu fi npadà bọ̀ lẹ́ẹ̀kejì?
**Johannu 14:3**
Bi mo bá si lọ ipèsè àyè silẹ̀ fun nyin, emi o tún padà wá, emi o si ______ _______ lọ sọ́dọ̀ emi tikarami; pe nibiti emi gbé wà, ki ẹnyin le wà nibẹ pẹlu.

Àkíyèsí: Ohun tó jẹ́ ìdùnú Jesu níti ipadabọ̀ Rẹ̀ lẹ́ẹ̀kejì ni wípé, yio wá kó awọn ọmọ Rẹ̀ lọ sí ilé ológo ti O ti pèsè silẹ̀ fun wọn. Kò sí omijé, orí-fífọ́, àìsàn tàbí ibà mọ́. Ṣùgbọ́n, ayọ̀, ati alaafia tí kò se e fẹnusọ títí ayé ni a ní.

# Èsì Rẹ

Jesu nbọ̀ ni ofurufu láìpẹ́. Ṣe wà á pinnu ní bayi lati múra sílẹ̀ lati pàdé Rẹ̀?

ÌDÁHÙN: _____________

# Àfikún

Ipele yi pèsè àfikún ìròhìn lati kẹkọ tẹ̀síwajú.

### Èròngbà nípa Rapture Bònkẹ́lẹ́

Èròngbà nípa ti Rapture ìdákẹ́jẹ́ dá lori agbègbè mẹjọ ti awọn eniyan gbà tọwọ́-tẹsẹ̀, tí wọn sì tún gbà pé òtítọ́ ni, ti wọn kò sì tẹsẹ̀ dúró lati wadi. Síbẹ̀, idanilójú tiwa ni lati má a wá inu Ìwè-Mímọ́ lojoojumọ lati mọ̀ bóyá nkan wọnyi rí bẹ́ẹ̀ (Iṣe Awọn Aposteli 17:11). Awọn èròngbà mẹjọ lórí Rapture bònkẹ́lẹ́ náà nìwọ̀nyí:

1. Rapture náà jẹ́ ìdákẹ́jẹ́.
2. O jẹ́ èyí ti a kò le è fojú rí.
3. Rapture náà yio fi awọn ẹni búburú silẹ̀ láàyè.
4. Ọlọrun mu awọn olododo kúrò lati da àbò bò wọn kúrò ninu ìpọ́njú.
5. Wíwá Jesu lẹ́ẹ̀kejì yio jẹ́ ìpele mejì: (1) Rapture ìdákẹ́jẹ́ náà ati (2) wíwá èyí ti yio jẹ ninu ògo.
6. Ìpele mejì ti wíwá Jesu wọnyí yio jẹ́ ìwọn ọdún meje sí ara wọn.
7. Rapture yíò kọ́kọ́ ṣẹlẹ̀ kí a tó fi Aṣòdì sí Kristi hàn, ẹniti yio mu ìpọ́njú wá.
8. Awọn ẹni búburú yio ní ànfaní ìgbà kejì ní ikorita yi lati yipadà ki wọn sì jọ́sìn sí Kristi.

Lati ṣe àyẹ̀wò àwọn kókó wọnyi ní ẹ̀kún rẹ́rẹ́, ó gbọ́dọ̀ ju àlàyé lórí àfikún kékeré yi lọ, ṣùgbọ́n a o sáré ṣe àlàyé lorí ọkọọkan nihin. A parí àlàyé lori kókó èkíní ati ìkejì ninu ẹ̀kọ́ yi, ṣùgbọ́n a tún ún mẹnu bà wọn fun atẹnumọ́. Múra sílẹ̀ fun awọn ìyanu kan!

1. Rapture náà ki iṣe ìdákẹ́jẹ́ ṣùgbọ́n yio jẹ́ ti aláriwo nlá gidigidi. Ìwé-Mímọ́ wípé Jesu yio sọ̀kalẹ̀ "pẹ̀lú ARIWO, pẹ̀lú OHÙN OLÓRÍ AWọn ANGẸLI, ati pẹ̀lú ÌPÈ ỌLỌRUN." 1 Tessalonika 4:16, a tún tẹnumọ́ ọ́n. Dafidi wípé, "Ọlọrun wa mbọ̀, ki yio si dákẹ́:..ẹ̀fufu líle [ìjà, ìjì] yio sì má a jà yi i ka kiri." Orin Dafidi 50:3. Jeremiah pẹ̀lú wípé, "OLUWA yio kọ lati òkè wá,...yio si kọ sori ibùgbé rẹ, yio pariwo. ... Igbe kan yio wà titi dé òpin ilẹ̀ ayé." Jeremiah 25:30,31. Kò sí ohun kan ninu rẹ̀ tó jẹ́ ìdákẹ́jẹ́! Kristi yiò wá pẹlu ariwo ti a o gbọ́ ní gbogbo ayé. Fiyè si eleyi daradara. Bí o bá wà láàyè nígbàtí Jesu ba dé, wà á gbọ́ bi Ó ti nbọ̀. Etí rẹ yio dún pẹlu igbe nlá tó le è ba etí jẹ́.
2. Rapture náà ki iṣe èyí ti a kò le è fi ojú rí; gbogbo eniyan ni yio ri i. Gbogbo awọn angẹli ni yio wá pẹlu Jesu (Matteu 25:31). Angẹli kan soso ni o farahàn ní ìgbàtí Jesu jinde pẹ̀lú ìmọ́lẹ̀ rẹ̀, èyí tó lagbára debi wípé gbogbo àwọn olùsọ́ Romu subú lulẹ̀, wọn sì dabi òkú (Matteu 28:2-4). Ṣe agbéyẹ̀wò bi ìmọ́lẹ̀ gbogbo awọn angẹli ọrun yio ti tó! Afikún ògo awọn angẹli li ògo ti Jesu tikalarẹ (Matteu 25:31) ati ògo Baba Rẹ̀ (Matteu 16:27). Ìmọ́lẹ̀ náà yio jẹ́ èyí tó lẹ́rù lọ́pọ̀lọpọ̀. Jesu tún wípé, Nítorí gẹ́gẹ́ bi manamana ti ikọ lati ilà-oorùn ti isì mọ́lẹ̀ dé ìwọ̀-oorùn; bẹ́ẹ̀ni wíwá Ọmọ-eniyan yio rí pẹ̀lú. Matteu 24:27. Ṣé bonkẹ́lẹ́ ni? Ki iṣe ìtàn agbórí-rò. Lotitọ, Bibeli ti yanjú èyí títí láí nígbàtí ó wípé, "Kiyesi i, o mbọ̀ ninu awọsanma; gbogbo ojú ni yio sì ri i. Ifihan 1:7. Ó dájú wípé, bí o bá wà láàyè nígbàtí Jesu bá dé lẹ́ẹ̀kejì, o ó ri I bí o ṣe nbọ̀!
3. Rapture náà kò ní fi awọn eniyan búburú sílẹ̀ rárá. Ṣùgbọ́n a o pa wọn ni ipadabọ̀ Jesu (Isaiah 11:4; Malaki 4:1; 2 Tessalonika 2:8).
4. Ọlọrun kò ní kó awọn olododo kúrò ninu ìpọ́njú náà, ṣùgbọ́n yi o pa wọn mọ́ ninu rẹ̀ ni (Orin Dafidi 91:5-12).
5. Ìpadàbọ̀ Jesu lẹ́ẹ̀kejì kò ní jẹ́ ìpele méjì èyí ni pé oni bònkẹ́lẹ́ ati èyí ti gbogbo eniyan yio rí. Ọkan soso ni ipadabọ̀ lẹ́ẹ̀kejì, ati wípé gbogbo alàáyè eniyan tó wà ninú ayé ni yio rí I. Kò sí Ìwé-Mímọ́ kankan to faramọ́ ìpadabọ̀ Jesu lẹ́ẹ̀keji pé onipele méjì ni.
6. Awọn ẹlẹ́kọ rapture tún gbà wípé, ọdún meje ló wà laarin ipele mejeeji ipadabọ̀ Kristi. Eleyi kò bá Bibeli mu.
7. Aṣòdì sí Kristi kò ní farahàn ni ọdún mẹta ààbọ̀ lẹhin ipadabọ̀ Jesu lẹ́ẹ̀kejì. O ti nsisẹ́ lati ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọdun (1 Johannu 4:3) ati wípé, ó sì nṣe iṣẹ́ ibi rẹ̀ títí di ìṣinsìnyí.
8. Awọn ẹni búburú kò ni ànfàní ìgbà kejì lati di ẹni ìgbàlà lẹhin ipadabọ̀ Jesu lẹ́ẹ̀kejì. Gbogbo ẹlẹ́ṣẹ̀ ni a o parun ni ìgbà ipadabọ̀ lẹ́ẹ̀kejì. Kò sí ànfàní ẹ̀ekeji fun ẹnikẹni lẹ́hìn ipadabọ̀ Jesu lẹ́ẹ̀kejì.

©2012 Ilé-iṣẹ́ Òtítọ́ Ìyanu
Àṣẹ ati Ẹ̀tọ́ lati tẹ ìwe yi jáde wa fún
Tí a tẹ̀ jade ní ìlú Amẹrika

AMAZING FACTS
P.O. Box 909
Roseville, CA 95678



YOR-SP3.indd 2
5/23/13 1:46 PM